4/6/77
IBADAN.

WEEKS 45&46
Kongi WK 45
2 19 38
Wk 46
17 28 47
Asiko BK WK 45
11 21 33 55
Wk 46
49 53 54 57
Ross Wk 46
29 & 40
WK 46
53&45

# Imọlẹ Owurọ

ẸSIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 45
NAP 4 16 22
Perm 4 16 19 22 31
My Address ?
Not nessesary,
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
**1 23 24**

Independent Paper Vol. XV NO 803, SATURDAY MAY 4. – FRIDAY JUNE 10, 1977 10K. (KOBO MEWA)

14 JUN 19

# IYA ARUGBO DA WARIWARI JO ADIGUNJALE !

IYA ARUGBO kan ti ba iṣẹ jẹ mọ awọn adigunjale lọwọ, o si ti gba owo ti o fẹrẹ to ọkẹ kan-abọ Naira (₦39,082.00) ju silẹ lọwọ awọn adigunjale na.

Ni abule Idogbo, ibuṣọ mẹjọ si ilu Ibinni ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ ninu ọsẹ yi.

Irohin fi ye wa pe, awọn adigunjale na ti nwọn to mẹrin ni nwọn dira ogun wọ ile iṣẹ Mandona Organisation ti nta eroja ikọle ni adugbo Akpakpara ni ilu Ibinni, nwọn yọ ibọn si Mọsinja ile iṣẹ na, nwọn si fọ seefu ti ile iṣẹ na ti owo ti nwọn pa ṣa aaju ọjọ na wa.

Irohin sọ pe iye owo gidi ati ṣẹẹki ti awọn ole na ko nibi idigbolu na jẹ ₦39,082.69.

A gbọ pe lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ru owo na sinu mọto ti nwọn gbe wa, nwọn si wa mọto na lọ l'ẹsẹkẹsẹ.

IYA ARUGBO

Irohin fi ye wa pe abulẹ kan ti njẹ Idogbo ti iṣe buṣọ mẹjọ silu Ibinni ni awọn ọlọṣa na gbe owo na lọ.

Nwọn sọ pe nigbati nwọn de ibẹ, nwọn wọ

(Woju Ewe Kẹjọ)

## Olopa ji owo Odaran gbe

ILE-IṢẸ Ọlọpa ni Ipinlẹ Bendel, ti yọ ọkunrin Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ kan n'iṣẹ bi ẹni yọ jiga lori jijẹbi ẹsun pe o ji owo ọdaran kan gbe. Ogun Naira ni nwọn pe owo na.

Ọga Ọlọpa Ipinlẹ na, Ọgbẹni Etim O. Inyang l'o kede ọrọ na fun awọn oniwerohin. O ni yatọ si pe awọn gba aṣọ l'ọrun Ọlọpa na, o tun nilati lọ sile ẹjọ lati koju esun ole jija.

Irohin fi ye wa pe, Ọlọpa ti a wi yi ni nwọn fi ti ọdaran kan pe ki o maa ṣọ ọ; ṣugbọn nigba ti ọdaran na tọrọ aaye pe oun nlọ tọ, ni ogun Naira ba bọsilẹ ni apo ọdaran na bi o ti nlọ.

Irohin fi kun un pe nihin ni Ọlọpa na ti sare mu owo na ti o si ju u si apo ọta ibọn rẹ. ṣugbọn nigba ti ọdaran na pada de ti o beere bi Ọlọpa na ba oun ri owo oun ti o bọsilẹ, Ọlọpa na sọ pe oun ko ri i.

Siwaju si i, nwọn ri nibi ti ọdaran na ti nwa owo na kiri ni ẹnikan ti o duro si tosi ibẹ sọ pe, oun fi oju ara oun ri i pe Ọlọpa na l'o mu un ati pe ninu apo ọta ibọn rẹ ni o fi i pamọ si.

Nihin ni ọdaran na ti fi igbe ole bọnu. Nwọn ni nigba ti nwọn yẹ inu apo ọta ọwọ Ọlọpa na wo nitootọ, nwọn ba owo na nibẹ.

Bakauna ninu ọrọ rẹ, Ọga Ọlọpa na sọ pe bakanna ni awọn ti le awọn Ọlopa diẹ kuro l'ẹnu iṣẹ fun oniruuru ẹsẹ irufin ti nwon da l'ẹnu iṣẹ.

## Tunde Akran di Oba Agbada

NI aipẹ yi ni nwọn de gbajumọ oniwerohin kan nilu Eko, Ọmọ Ọba Godwin Babatunde Akran ni ade gẹgẹ bi Ọba ilu Agbadarigi (Badagry) ni Ipinlẹ Eko.

Ọga kan pataki ni Ọba titun na jẹ ni ile iṣẹ iwerohin New Nigerian ki o to gori itẹ awọn baba rẹ



Orukọ oye rẹ lori itẹni Alaiyeluwa Godwin Babatunde Akran, Aholu Mẹnu Toyi Kinni ti ilu Agbadarigi

Aworan ẹgbẹ yi nfi Ọba titun na han bi nwọn ti nki i ku orire.

## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE 58

Lawuyi Ogunniran
ỌỌKU l'oni, Alajao mi
Ajao, o o la, o o ni i tẹ.
Iyawo re nkọ
Ṣe nbẹ l'alaafia ara?
Ẹẹ ya, ẹẹ ra, ẹ ni i tẹ.
Ẹ ku ooru-atojo yi,
Ẹ ku aitete r'agbado jẹ,
Ẹ si ku asiko eyi
K'Ọba Oluwa jẹ k'o dun
K'o si yun fun gbogbo wa.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O kare l'aiye ọmọ Ejigbọjọ
Oo ni i tẹ, o o ni i rare,
Okele ko ni i ha ọ l'ọrun,
Omi ata o ni i pa ọ l'ori.
O ku ipade t'o kọja nibi,
O si ku amojuba titun ;
Jẹ ka tete bẹrẹ ipade
K'a ma l'akoko ṣofo.
L'ọsẹ t'o kọja nibi,
O sọrọ, o si ṣalaye
L'ori oṣo ati ajẹ pupọ ;
O si tun sọrọ ṣoki
Pe, o mọ ohun t'alakọwẹ gbojule
Ti nwọn fi nsọ pe,
Oṣo at'ajẹ ko si nilẹ wa ;
Ṣugbọn o ko sọrọ yi
Ti a fi tuka n'ipade t'o gbẹyin.
Nitorina ọmọ Ejigbọjọ
Mo fẹ ki o tara sọ fun wa.
Ohun t'ọlọmọwe ri
Ti nwọn fi nsọ 'ru ọrọ bẹẹ.
Lawuyi Ogunniran
O kare l'aiye-bẹẹ l'a kuku bi ni
Mo si fẹ ki o tẹti bẹlẹjẹ
Ki o gbọ 'di ọrọ.
Ki i ṣe pe gbogbo alakọwe
L'o sọ pe oṣo at'ajẹ ko si;
Ogede awọn
T'o kẹkọ imọ ijinlẹ
Nipa ohnn afọwọṣe ni.
Ki i si ṣe gbogbo wọn kede,
Ki i ṣe gbogbo wọn delẹdelẹ
Bi ko ṣe awọn eniyan kan
Ti nwọn ka a ninu iwe,
Ti nwọn si gbagbọ pe,
Ohun ti a ba le foju eni ri laiye
Ni a le sọ pe o nbẹ ninu aiye
Tabi ohun ti a ba le fiye
Pe, o nbẹ bi ko tilẹ ṣe e ri
Gẹgẹ bi afẹfẹ,
Gẹgẹ bi ooru ati bẹẹ bẹẹ lọ.
Iru awọn eniyan
T'o ba gba imọ yi gbọ
Ni nwọn ko gba
Pe, oṣo, ajẹ tabi emere nbẹ
Ninu aiye wa.
Nitorinaa, ọmọ Ajiṣegiri;
Idi ọrọ ree
Ti a fi r'ọlọmọwe
Ti nsọ pe ko si oṣo ko si ajẹ,
Ko s'oloogun ika,
Ko si si emere.
Ṣugbọn mo tun fẹ ki o ye ọ
Pe, ọpọ alakọwe t'o daju
Ti kii ṣe ẹlẹkọ imọ ijinlẹ,
Ati ọpọ ti ko kawe to nkan
Ni o maa nsọ pẹlu
Pe, ko si oṣo ati ajẹ
Ati oloogun ika.
Ṣugbọn ti o jẹ pe
Bi ẹ ba pe ki nwọn sọ idi
Nwọn ko le ri nkan sọ
Bi ko ṣe pe ohun ti awọn kan nwi
Ni awọn na ntẹle sọrọ.
Idi ọrọ ree o, Alajao mi,
Ti a fi r'ọpọ ọlọmọwe
Ti nsọ bẹẹ kaakiri
Bẹẹ ni, nwọn ko mọ ẹwẹ ni,
Nwọn ko si mọ owe;
Alakọwe ko mọ oogun
Nwọn npe e l'ẹfọ;
Idi pataki niyi
Ti a fi rọpọ ọmọwe
Ti nsọ pe, Ọlọrun ko si!
Nwọn ni Ọlọrun ko si
Nwọn ni ko s'eṣu nibikan !
Nitori nwọn ni,
Ohun t'awọn ko ba fojuri
Awọn ko le gbagbọ rara
Pe o nbẹ nibikankan.
Ajao, jẹ k'a jami l'ori ọrọ
Iru awọn eniyan wọnyi
Nitori nwọn le mu ni ṣi ọrọ wi,
Nwọn le mu ni ṣi ọrọ sọ,
Nwọn le mu ni ṣi iwa hu
Bi a ba nsọ ọ delẹdelẹ.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ayinde, ọmọ Ejigbọjọ,
Eetiri, ṣe ko si nkan ?
Ki l'o fẹ ṣiwọ ọrọ si
Nipa alakọwe asiko ?
Asiko ti a ngbadun alaye
L'o fẹ ṣiwọ ọrọ na ni ?
Tabi o ko mọ pe
Ẹkọ t'o daju l'a nri kọ
Ninu alaye rẹ ni ?
Ki l'o fẹ dakẹ si,
Ki l'o mu ọ fẹ daale ?
Tabi o nbẹru ọmọwe
Ki nwọn ma baa bugada
Ki nwọn fa ọ de kootu ?
Ṣe ki i ṣe ẹru ofin ni nba ọ
Ti o fi fẹ ṣiwọ, ọmọ Ejigbọjọ ?
Bi ki i ba ṣe tori eyi,
Mo fẹ ki o maa b'alaye rẹ lọ
Nitori ẹkọ pataki l'a nkọ
Ninu gbogbo rẹ delẹ
Lawuyi Ogunniran
Ng ko bẹru alakọwe
Ng ko si bẹru ẹjọ;
Ng ko si bẹru
B'alakọwe pẹyinda
Ti nwọn nbu mi nigbakigba;
Ṣugbọn mo fẹ ki o mọ pe,
Asọgbeti l'ẹrọ wọn ni,
Iti ọgẹdẹ l'ọrọ alakọwe jẹ
Ko t'ohun a le lọ ada ti
Nitori, ọpọ alakọwe
Ki i f'ọgbọn ọlọgbọn ṣọgbọn,
Nwọn ki i kọ ẹkọ kun ẹkọ
Nwọn ki i gba imọ
Lati ọdọ ẹlomiran;
Nwọn a maa foju tẹnbẹlu ẹda
Nwọn a ni
Ko s'ẹni t'o mọ bi awọn,
Nwọn a si gbẹkẹle
Ogede imọ ti nwọn ka ninu iwe
Nwọn ki i da inu tiwọn ro
L'ori ọpẹlọpọ ọrọ.
Ṣugbọn nitori ọrọ ti o wi
Pe, o fẹ kẹkọ

(Wo Oju Ewe Kẹfa)


## Asiko Nap

# 2
# 4
# 9

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ,
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi. Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17. Ilọrin

# Ẹgbọ t'emi

## Awon awako ko gboran

OLOOTU,

O ya mi l'ẹnu pe bi iwerohin, redio ati Ijọba ti nkigbe tantan fun awọn awakọ to lati maa ṣe pẹlẹpẹlẹ, nwọn ko gbọ rara.

Bi enia ba ri i bi awon dẹrẹba ṣe maa nwako ni ilẹ wa, oluwarẹ yio ri i pe, nwọn ko tilẹ bikita fun ẹmi ọmọnikeji pẹlu.

Nitorina, ki ba dara bi Ijọba kuku ṣe ofin pe, ẹnikẹni ti o ba wa mọto pa enia nipa are asaju, aitẹle ofin irinna, ọti amuyo ati taba igbo mimu, ẹwọn ọdun mẹẹdọgbọn ni ki o lọ ki nwọn si gba iwe aṣẹ iwakọ rẹ pe, iru ẹni bẹẹ ko gbọdọ wakọ mọ lailai.

Emi ni,
Ajani Iyowuawi,
Abẹokuta.

## E tun ofin amugbo se

OLOOTU,

MO ki Ijoba Ologun Apapo fun gbigbogun ti iwa buburu gbogbo ti o nbẹ ni ilẹ wa paapaa nipa ṣiṣe atunṣe si ofin afipajale.

Mo wa fẹ ki Ijoba Ologun Apapo mo pe, igbo mimu ni o nran oniruuru iwa buburu gbogbo lowo ni ilẹ wa nitoripe, igbo ni awon adigunjale maa nmuyo ki nwon to lo si oko ole.

Bakanna ni opo awako oniwakuwa jẹ amugbo; opo iwa jagidijagan ti o si wa kaakiri ile iwe giga ni ilẹ wa jẹ nipa iranlowo igbo mimu.

L'ode oni, igbo mimu ti di baraku fun awon odomokunrin wa, opo omobinrin aṣẹwo l'o si nmu igbo.

Nitooto ni ẹwon odun mẹwa fun igbo mimu le fẹ jo bi ẹni pe a ko laju bi i ti ilu Oyinbo l'odo wa, ṣugbon emi fẹ ki Ijoba Apapo mo pe, alaafia ati ifokanbalẹ enia orilẹ-ede yi ṣe pataki ju eebu ti ara ilẹ okere le bu wa lo.

Bi nwon ba so pe a ko laju l'a fi nju enia si ẹwon odun mẹwa nile tiwa, ṣugbon ti alaafia ba wa fun wa, ko ṣe nkankan. Nitorina, mo ro Ijoba Apapo lati ṣe atunṣe si ofin igbo mimu nipa pe ki ẹnikẹni ti o ba jẹbi ẹsun pe nwon ka igbo mo on lowo maa lo si ẹwon odun mẹwa o kere tan ki ẹni ti o ba ni ọpọ idi igbo lowo lo si ogun odun, ki ẹni ti o ba nda oko igbo si lo si ẹwon gbere.

Emi ni,
Tiamiyu Adewuyi,
Ọyọ.

## 32

## Ki l'o fa a ?

OLOOTU,

Mo ki nyin pupo fun akitiyan nyin lati mu ki ede Yoruba goke agba.

Ng ko mọ ohun ti o fa a ti o fi jẹ pe oju ewe mẹjo pere ni iwe nyin maa njẹ lati ojo yi wa.

Nitoripe, iwe na dara pupo, eto inu rẹ nilaari, ẹ ki i tẹ oro aiyẹ, ẹ ki i purọ, e ki si bẹru lati duro ti otito, bẹẹ ni ori nyin pe pupọ.

Bakanna ni o jẹ pe ountẹ iwe ny'n dara. Ki lo wa dẹ ti iwe na ko ti i ju oju ewe mẹjọ lọ lati ojo yi wa ?

Ibeere keji ni pe, iru enia wo ni o wa ni ẹhin korẹesi Naira yẹn ? Ki l'o wa de ibẹ ? Kini oruko rẹ ti njẹ ? Ṣe a fi ṣe iranti rẹ ni ?

Emi ni.
Ọladokun Aiyenfaajo
Ibadan.

AKIYESI

Ọrẹ wa Ọladokun, Idahun l'ori ibeere akoko ni pe, "Bi a ti ni itan mo ni a fi i han oko ẹni" ṣugbon a ngbadura ki a ni itan ju bẹẹ lọ eyi ti a o maa fi han oko wa; ti oko wa yio maa wo; ti inu rẹ yio si maa dun.

Idahun keji ni pe, a fi aworan okunrin na pe omo Naijiria ti o jẹ agbẹ ti si nṣa odi ẹyin ti a fi nṣe epo pupa lọwọ. A wa fi epo pupa han gẹgẹ bi ohun t'o mu oro aje ilẹ wa gbegba oroke. Idi ti aworan na fi wa nibẹ ni a soyi; bi a ba si ṣakiyesi gbogbo owo korẹẹsi wa yoku, a o ri i pe o fi oniruuru ohun ti a fi nṣe ọrọ aje ni ilẹ wa han ni.

—OLOOTU

## Nje Ododo ni ?

OLOOTU,

MO gbadun " Itan Omi ati Eko " ti Ọlola Atioro omo Atiala npa sinu Imolẹ Owuro pupo nitoripe o tun ran wa leti awon oro atijo ti a maa ngbo lati ẹnu awon baba wa.

Ṣugbon kinikan ni mo fẹ beere lowo Olootu nipa oro na. Njẹ ododo ni pe, kọkọrọ omi nbẹ lowo Eleko ati pe, ni ojokojo ti Eleko ba binu o le ṣi kọkọrọ omi silẹ ki omi si gbe gbogbo Eko lọ ?

Emi ni,
Iyanda Saka,
Eko.

AKIYESI

Ọrẹ wa Iyanda,
Ko ri bẹẹ rara. Ko si kọkọrọ omi yowu lowo ẹnikẹni debi ti t'Eko yio tilẹ wa wa lọwọ Ọba Eko. Itan atọwọdọwọ lasan ni.

— OLOOTU

KEREO

GBOGBO - ENIA!
fun

•Ipolowo oja ati Ikede,
•Akiyesi ati Itufọ,
•Iranti oku ati Ikede Ariya,
•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
•Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ.SA KỌWE TABI KI O WA RI :-

Advertisement Manager:

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496B YEMETU ALADORIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Akéde ọ̀nà Iyè

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# Olotito ntan lo ninu awon omo enia (5)



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"ẸNIKẸNI ti o nrin ọna ayidayida, enia buburu ni ṣugbọn oninu funfun ni iṣẹ rẹ tọ", Owe 21; 8.

Lati ọsẹ marun sẹhin ni a ti nkigbe tantan pe, Olotitọ ntan lọ ninu awọn ọmọ enia. Njẹ ko yẹ ki iru ọrọ yi ti enia l'oju pe, olootọ ntan lọ ninu awọn ọmọ enia ?

Olukuluku enia ninu aiye l'oni ni o yẹ ki o jẹ itiju fun lati gbọ pe olotitọ enia ntan lọ ninu awọn ọmọ enia nitoripe ibikibi ti otitọ ba ti ntan lọ ko ṣai ni wa ninu ewu gbogbo gẹgẹ bi ile aiye ṣe wa l'oni yi.

Ṣugbọn ọmọ aiye yi na ni alaiṣootọ na ti o kun inu aiye, ẹnikẹni ti o ba si jẹ alaiṣootọ ni yio gba itiju nitoripe alaiṣootọ enia ni oju yio ti.

Njẹ bi onile kan ba gbe ile rẹ fun abani—gbowo ti nwọn npe ni Caretaker lati maa ba a gbowo rẹ; ṣugbọn ti awọn enia ranṣẹ si onile na ni ilẹ okeere ti o wa pe ki o tara wa sile nitoripe abanigbowo ti o gbe ile fun ti bẹrẹ si i nawo rẹ ni inakuna, njẹ onile na ko ni i wale ?

Njẹ nigba ti onile ba de lati idalẹ ti o wa duro si ita ile rẹ pe, oun de o, ki gbogbo awọn onigbese ati awọn ti nhuwa ibi, awọn ti ko ni i kọle l'aiye ti nwọn nko owo oun na, ki nwọn jade si oun, taa ni ẹnyin enia ro pe oju yio ti ninu ile na ? Dajudaju, abanigbowo ti o ko owo jẹ ni yio gba itiju ṣugbọn awọn ayalegbe ti nwọn nsan owo deede ti iwe ẹri si wa lọwọ wọn yio ni inu didun ati igboya, okan wọn yio si balẹ fun ohunkohun ti o wu wo fun onile.

Nitorina iwọ ọmọ enia ti a fi ṣe Olori ninu Ijọ, ninu ile, ninu ilu ati nibi yowu ki o le jẹ olori fun, otitọ ati ododo ni ki o maa fi lo ipo na nitori nkan wọnyi ni imọlẹ ti o le ṣe enia l'oore l'ọdọ rẹ.

Olori ati aṣiwaju gbọdọ salọ, ti ododo yio si jẹ olori. Bibeli wi pe, "Ẹni ti o fi ẹtan bo irira mọlẹ, iwa buburu rẹ li a o fi han niwaju gbogbo Ijọ," Owe 26; 26.

Nitorina ẹnyin Ojiṣẹ Ọlọrun ni agbaiye, ẹjọ ki a kun fun otitọ ati ododo ki a ma baa jẹbi toripe Ọlọrun ko d

a

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

ki o de.

Nitorina, mo nwi fun nyin l'oni, ẹnyin aṣiwaju Ijọ yowu ti o le jẹ ti o ba nfi eke, irọ, aiṣododo ati ọna ayidayida ko owo jọ fun ifẹkufẹ ara tobẹẹ ti ọmọ Ijọ ati awọn alaigbagbọ ko fi ri ẹkọ kọ lara yin pe, ki ẹ tete ronupiwada. Tabi kii ha ṣe itiju ni o jẹ fun nyin ẹnyin ti ẹ pe ara nyin ni Ojiṣẹ Ọlọrun lati maa huwa ti yio mu ki otitọ tan patapata ninu aiye ?

Ṣugbọn bi o ba jẹ pe otitọ ati ododo si nṣiṣẹ rere ninu Ijọ rẹ titi di bi o ṣe nka iwe a jẹ pe iwọ ni a le fi we ayalegbe ti o nsan owo ile ti o ngbe deede, ko si si ifoiya fun ọ mọ.

Ṣugbọn iwọ aṣiwaju tabi Ojiṣẹ Ọlọrun ti o ko ba fi apẹrẹ rere lelẹ ni ipokipo ti o ba wa fun awọn ara ẹhin, iwọ ni a le fi we abanigbowo ti o ba onile gba owo ti o si na owo na, ẹni ti a o dojuti ni gbangba l'oju ọmọde ati agba.

Bẹẹ gẹgẹ ni gbogbo awa ẹda enia ri ninu aiye. Awọn ti ko sọ otitọ ti ko si ṣe ododo ni nwọn wa ni ile aiye yi gẹgẹ bi ẹni ti o ya ile onile gbe ti ko sanmaa fi apẹẹrẹ rere lelẹ fun ọmọ ẹhin gẹgẹ bi a ti ntẹnumọ ọn fun nyin, nitoripe aili apẹẹrẹ rere lelẹ ati ai fi otitọ ati ododo dari ohun gbogbo, lewu fun awọn enia orilẹ-ede aiye.

Nitorina iwọ ọmọ enia, ọrọ Ọlọrun nketantan fun ọ pe, iru iwa ikọkọ yowu ki o maa gbe ikọkọ hu ti o si nro pe enia ko ri ọ, mo nwi fun ọ l'oni pe, akoko nbọ ti Ẹni ti o ni aiye ati ọrun yio ṣiṣọ loju okukun, ti ẹtan yio wa si lasan bikoṣe lati jẹ apẹrẹ fun awọn ara ẹhin.

ADURA

Oluwa Ọlọrun Ọrun Oun aiye, Ọrọ gbe inu ọmọ enia fọhun: Jọwọ; maṣe jẹ ki ng padanu Ijọba Ọrun. Ma si ṣe jẹ ki ohun iṣina aiye yi fa mi si ọna aiṣotitọ ki a le kẹkọ rere l'ara mi, Aamin.


**Wanted**

APPRENTICES and advanced apprentices are wanted in our Printing Section.

Remuneration is very attractive. Bring your application by hand to the Manager:

NIGERIA NEW STATES CO;
18, Ọdunlami Street,
Lagos.



**NIGERIA NEW STATES CO.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



**IWE ỌRỌ ỌLỌRUN**

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# Darandaran lu darandaran pa

IROHIN lati ilu Kaduna ni Oke-Ọya fi ye wa pe, nwọn ti mu ọkunrin darandaran kan Basso Jaye wa sile ẹjọ Chief Magigtrate kan nilu na lati koju ẹsun ipania.

Ẹsun ti nwọn ka si ọdaran na l'ọrun ni pe, o lu darandaran ẹlẹgbẹ rẹ kan, Jaye Baze ti awọn mejeeji ngbe abule Tsawa Kidandan ni agbegbe Giwa, Zaria pa ni ọjọ kẹta oṣu keji ọdun yi.

Ripẹtọ Ọlọpa kan Ọgbeni Hamidu Inuwa ni o nka ẹsun si ọdaran na l'ọrun. O ni lẹsẹkẹsẹ ti Basso Jaye lu ekeji rẹ pa ni o dana sun oku rẹ.

Ọga Ọlọpa na sọ pe, iwadi ti pari bayi l'ori ọrọ na ati pe iwe eto ẹjọ na ti kọja lọ sile eto akoso ọran ofin ni Kaduna; o si rọ ile ẹjọ lati fi ọjọ ipade ẹjọ na si akoko gigun.

Nigbana ni Adajọ sun ẹjọ na di ọjọ kọkandinlogun oṣu keje ọdun yi ṣugbọn o paṣẹ pe ki nwọn lọ ti ọdaran na mọ ọgba ẹwọn.

# Oga Soja digbolu dereba Soja

ỌGAGUN Olu Bajọwa ti iṣẹ ẹkan pataki ninu awọn ọga eto iṣẹ Ologun ti digbolu awọn kan ti o pe ni oniwakuwa ninu awọn dẹrẹba Ologun.

Nilu Eko ni Ọgagun Bajowa ti sọrọ na nigbati o nba awọn ọgalọga nibi eto ẹka onimọto ti ibi iṣẹ Ologun sọrọ.

O ni oniruuru irohin ti ko dara ni awọn ngbọ nipa iwakuwa ti o kun ọwọ awọn dẹrẹba Ṣọja, ai ka ofin irinna si ati iwa alailẹkọ ti o kun ọwọ wọn ninu iwa ati iṣẹ wọn.

Ọgagun Bajọwa sọ pe, awọn enia ti sọ awọn awakọ Ṣọja l'ẹnu nipa iwa buburu na, o si kilọ fun wọn lati ronupiwada laarin oṣu kan.

Nigbana ni Ọgagun Bajọwa paṣẹ fun oludari eto mọto fun iṣẹ Ologun, Ọgagun P. Arokoyo lati ṣe iwadi l'ori bawo ni dẹrẹba Ṣọja se njaamu ju ki o si ro iru ọna ti ijanba mọto yio fi dinku gidigidi ni oju awọn ọna wa.

# Akeko lu akeko pa

AWỌN Ọlọpa ilu Enugu ni Ipinlẹ Anambra ti mu akẹkọ kan l'ori ẹsun pe o lu akẹkọ ẹlẹgbẹ rẹ kan pa.

Ọdaran akẹkọ na ti o nka iwe kẹwa lọwọ jẹ ọmọ ile ẹkọ Immaculate Conception College nilu Enugu

Awọn Ọlọpa sọ pe akẹkọ ọlọdun keji kan, Peter Uzoigwe ti ilu Oturu, ni Okigwe ni nwọn lu pa ninu rogbodiyan na.

Irohin fi ye wa pe, awọn Ọlọpa nṣe iwadi gidigidi lọwọ l'ori ọrọ na bayi.

Ṣugbọn awọn alaṣẹ eto ẹkọ niha ibẹ ti paṣẹ fun awọn ọga ile ẹkọ kaakiri pe ki nwọn maṣe gba awọn akẹkọ ti o ti kawe jinna l'aye lati maa na awọn ọmọ ẹhin wọn ni inakuna.

Bayi, akọwe eto ẹkọ ni Ipinlẹ Anambra bẹ awọn ile iwe giga kan ni Ipinlẹ na wo, o si ba wọn sọrọ.

Akọwe na ni Ọgbẹni Innocent Ejikeme ẹni ti o bẹ ile ẹkọ giga Emene High School wo, ti o si kilọ fun awọn agba akẹkọ funra rẹ pe nwọn ko gbọdọ na ẹmọlẹhin wọn mọ.

## Oguns Nap

**2 3**

# Ejo kika Adajo l'eyin bere

AWỌN Ọlọpa ilu Ibadan ti mu ọkunrin kan ti awọn Ọlọpa sọ pe, omo Yoruba ni iṣe, Ganiyu Akanni wa sile ẹjọ Magistrate kan nilu Ibadan lati koju ẹjọ ẹsun pe o fẹ pa enia.

Ọkunrin na ni awọn afẹsunkanni ka ọran si l'ọrun pe ni ọjọ kẹtalelogun oṣu karun ọdun yi, o fẹ pa Adajọ ile ejo onipo keji karun Oloye Y. B. Ogundipẹ ni adugbo Mapo nilu Ibadan.

Awọn afẹsunkanni fi kun un pe ọdaran na digbolu Oloye Ogundipẹ o si pa a lara ninu idigbolu na.

Nwọn ko ti i gbọ ti ẹnu ọdaran na ṣugbọn Adajọ gba iduro rẹ, o si fi ọjọ ẹjọ na si ọjọ kọkanlelogun oṣu keje ọdun yi.

# Isoro n'igbesi

(Lati Oju Ewe Kẹta)

Ninu alaye mi ti mo ba ṣe,  
Ni yio jẹ ki ntẹsiwaju  
B'o ba d'ọsẹ t'o nbọ  
L'ori iwa alakọwe  
Ti ko gba p'oṣo atajẹ wa,  
Ti ko si gba pe  
Emere ati oloogun nbẹ  
Ninu aiye gbogbo.

**24 26 49**

**3 19 48**


# Aiyedetisola Commercial Electrical Store:

**Will satisfy all your electronics needs at resonable prices**

**Call at**

N27&41A I.C.C STALL  
AGODI GATE  
IBADAN




# Bosun Sowande Alasaro Arofo

Gbogbo enia ti o ba maa nteti si Redio WNBS atijọ ati Radio Nigeria Ibadan, yio ti mọ ẹni ti Alagba Bọsun Ṣowande iṣe.

Ni kukuru, Alagba Bọsun Ṣowande jẹ alarofọ atata ti enia ko le fi ọwọ rosẹhin. Ninu ki o le yi igbesi aiye enia si rere ni pataki ohun ti o maa njẹjade ninu arofọ Alagba Bọsun Ṣowande.

Bakanna ni Alagba Ṣowande jẹ ẹni ti o maa nfi igboiya sọrọ, a si maa sọ otitọ fun awọn olugbọ rẹ bi o ti wu ki jẹ BMLPS 11 fakiki. Ede Ẹgba ni o fi ṣe arofọ na gẹgẹ bi baba re Ṣobọ Aro-bi-odu alaṣaro-ọrọ ti i ṣe e nigba lailai.

Ẹnikẹni ti o ba tọ awọn agba lọ ni ilẹ Yoruba yio ri irohin gbọ nipa Ṣobọ Aro-

## Lati owo Bolaji Babalola

bi-odu gan-an, ẹni ti a gbe ọrọ kalẹ ni ọna ti o wu ni lori, oun ni baba. Nipa k'a fi ijinlẹ ede sọ arofọ, oun ni baba. Nipa k'a fi iriri aiye ko araiye lọgbọn, oun ni baba.

Gbogbo iriri aiye, ohun afojuri ati itan ti otitọ na koro to. Eyi gan-an l'o jẹ ki awọn enia fẹran arofọ rẹ.

Gbogbo nkan ti a wi yi gan-an ni Alagba Ṣowande fi ṣe agbekalẹ awo titun ti o ṣẹṣẹ ṣe ti a fẹ sọrọ rẹ yi.

Awo na ti nọnba rẹ jẹ BMLPS 11 fakiki. Ede Ẹgba ni o fi ṣe arofọ na gẹgẹ bi baba re Ṣobọ Aro-bi-odu alaṣaro-ọrọ ti i ṣe e nigba lailai.

okiki arofọ rẹ kan tobẹẹ ni ilẹ Yoruba ti nwọn fi maa nṣe orin kọ. Bakanna ni ewe iwoyi ti o ba ti ka iwe arofọ Ṣobọ Arobi-odu yi yio mọ pe, ọgbọn, oye, ẹkọ ati



ALAGBA BỌSUN ṢOWANDE
Ọmọ Ṣobọ Aro-bi-odu

imọran iyebiye pọ ninu rẹ.

Ko si iyatọ ninu arofọ na ati eyi ti Alagba Bọsun Ṣowande ṣe yi. Ni oju kinni awo na ni o sọrọ lori Ẹsan ati Ayọ. Agbọronu ati agbọ-yiwapada ni ọrọ arofọ na.

Ni oju keji ni Alagba Ṣowande sọ arofọ lori koko ohun mẹta yi: Fọgbọn ọlọgbọn sọgbọn, Ogun ati Ọmọ Iya mẹta.

Ọrọ akọnilọgbọn, ọrọ ikilọ ati itan ni awọn ọrọ na dale, Alagbo Ṣowande si fi awọn ọrọ na ṣẹ iwaasu l'ọna ti o jẹ pe, ẹnikẹni ti o ba tẹle ọrọ inu rẹ, aiye rẹ yio rọ ọ l'ọrun.

Awo na dara fun ọmọde ati agba, ọkunrin ati obinrin gẹgẹ bi ohun ikọgbọn ati igbadun.

Irohin ti o tẹ mi lọwọ l'ori awo na fi ye mi pe, l'ẹnu iṣe ti awo na jade, awọn enia ti bẹrẹ si i lọ ra awo na. Iwọ na tete lọ ra tirẹ ni ile ọja rẹkọọdu gbogbo tabi l'ọdọ olupinja awo na:

ANKERR SOUND,
86, Cementery St,
Ebutemẹta.



# Idowu Dada di Oga ota

NINU idije are ayo ti nwọn ṣe laarin awọn ọta Ipinlẹ Eko, eyi ti o waiye laipẹ yi, Ọgbẹni Idowu Dada ti o jẹ ọga awọn ọta Ipinlẹ Eko ni o tun bori nibi idije fun aaye na.

Lati ọdun mẹta sẹhin ni Ọgbẹni Dada ti o ngbe ni ọna Ikorodu, ti nṣoju agbegbe rẹ lati maa bori nibi idije na.

Awọn enia ti o tun powọle ọga ọta na ni Ọgbẹni Ọladiipọ Oni ti Ebutemẹta ati Ọgbẹni Taibu Ọdẹnikẹ ti Ilasamọja.

Ni Ebutemẹta ni idije ti ọdun yi ti waiye; Ẹgbẹ Ijinlẹ Yoruba ẹka ti Eko l'o si ṣeto idije na. Ẹgbẹ yi jẹ ẹgbẹ ti o nja raburabu fun igbega ede ati aṣa Yoruba.

Ninu ọrọ rẹ lẹhin idije na, Ọgbẹni S. T. Fakọya ti iṣe Alaga ọjọ na sọ pe, ori oun wu pupọ fun eto na ti a gbekalẹ daradara ti awọn adije si fi ẹmi ifgba abajade na wọle; o si kan saara si Ẹgbẹ Ijinlẹ Yoruba fun akitiyan rẹ lati mu ki aṣa wa ti o niyelori ma di ohun igbagbe.

Amoye kan fi ye wa pe, eyi jẹ itẹsiwaju aṣa ibilẹ wa, bẹẹ ni o si jẹ ipalẹmọ eto ti o nlọ lọwọ lati da ẹgbẹ ontayo silẹ ni ilẹ Naijiria eyi ti yio waiye ni oṣu kẹfa ọdun yi:

# Ejo Sodeinde

(Lati Oju Ewe Keji) ti gba lati gbe owo kalẹ fun iṣẹ na nigba ti nwon yẹ gbogbo iwe ti o wa nidi oro na wo ati pe, iwe ti Banki ACB wa ko si Cooperative Bank pe, onigbese ni ile iṣẹ Ṣodẹinde Brothers, ni o ba ona jẹ nipa eyi ti Banki Cooperative ko fi ya ile iṣẹ na lowo mo.

Siwaju sii, Agbẹjoro na npe akiyesi Adajo si eto ipari ija ti o waiye pe, ohun ti ipari na duro le lori ni pe ki Ọgbẹni Ṣodẹinde mu awon Oyinbo na pada wa si Naijiria ati pe Banki na (ACB) yio gbe owo kale.

Agbẹjoro na so pe nitori oro yi ni Ọgbẹni Ṣodẹinde fi mu alakoso eto okeere fun ile iṣẹ Allied mill, Ọgbẹni Featherson wa si Naijiria laarin ogota ojo. O ni ṣugbon kaka ki Banki na gbe owo kalẹ lati papo pelu Ṣodẹinde Brthers da iṣẹ na silẹ, nṣe ni Banki ACB kọwe ti o da awuyewuye silẹ na le Ọgbẹni Featherson lowo.

Agbẹjoro na tun nfẹ ki ile ẹjo gbagbo pe, ninu odun 1971 nigbati ile iṣẹ Ṣodẹnide Brothers fi opin si ajoṣepo won pelu Banki na, nṣe ni Ọgbẹni Kazzim ti iṣe Ọga Banki na halẹ pe oun nilati ri i pe oun

(Wọju Ewe Kẹjọ)

# Isinku Oyerinde Koyoyo

ỌPỌLỌPỌ enia lonile ati alejo–dudu ati funfun l'o pesẹ sibi isin isinku Ọjọgbọn Nathaniel David Oyerinde, Ọtun Ṣọhun Ogbomọṣọ eyi ti o waiye ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu karun ọdun yi.

Oniwaasu ọjọ na ni Dokita E. A. Dahunsi ti iṣe Akọwe Agba fun ajọ nla ti Onitẹbọmi ilẹ Naijiria.

Ninu ọrọ rẹ, Dokita Dahunsi sọ ọpọlọpọ itan nipa igbesi aiye oloogbe na, eni ti o pe ni ọmọwe gidi ati ẹni ti o ni imọ pupọ nipa ẹkọ Bibeli.

O so bi o ṣe jẹ pe oloogbe na kẹkọ ni Yunifasiti kan ni ilẹ Amẹrika ti o si gboye B.A. ati B. D.

Siwaju si i, Dokita Dahunsi sọ nipa iṣẹ rẹ gẹgẹbi olukọ ati oloye ilu; o si sọ oniruuru itan nipa idagbasoke ijọ Onitẹbọmi ati ti ẹkọ pẹlu ipa ti Oloogbe na ko ninu aniyan wọnyi.

Ara awọn ayẹyẹ eto isinku oloogbe na ni ti awọn ti o ti kọ n'iwe ri ti nwọn wa kọrin iranti kan fun oloogbe na. Awọn ọmọ ile ẹkọ rẹ, na so pe, Oloogbe Ọjọgbon Oyerinde ni o ko awon ni orin na ni aiye ijoun.

Irohin fi ye wa pe, awọn enia ho gee nigbati ti nwọn ri awọn ọmọ ile ẹkọ na bi nwon ti darugbo to ti nwon si nkorin na. Ara awon akẹko na ni, Alufaa (Oloye) S. A. Ige, Oloye Samuel Ojo Bada ti iṣe Bada Ṣaki ati bẹẹbẹ lo.

Lẹhin isin na ni nwon lo sinku oloogbe na, bẹẹ ni moto ayokẹlẹ ti o wo ilu na ni ojo ti a nwi yi koja kika; awon ojiṣẹ Ọlorun lati oniruuru Ijo Onigbagbo jakejado ilẹ Naijiria, awon omowe nlanla, oṣiṣẹ nlanla, borokinni omo Ogbomoṣo nlanla nile ati ni idalẹ, ati awon ologun pẹlu tomodetagba ilu Ogbomoṣo ni o ṣe ẹyẹ ti o galola fun oku oloogbe na.

Gbajumo akewi kan ni Ibadan, Ọgbẹni Ọlatubosun Ọladapo fi ewi dabira nibẹ l'ojo na, gbogbo enia l'o si yonbo rẹ.

A o ranti pe, oloogbe Oloye Ọjogbon Oyerinde ni o ko iwe Itan Ogbomoṣo ninu odun 1934.

# Adigunjale

(Lati Oju Ewe Kinni) inu oko rọba lọ lati bo owo na mọlẹ. Nwọn ni nibi ti nwọn ti nfẹ ṣe eyi ni ọkan ninu wọn ti nwọn pe ni dẹrẹba takiṣi tiwọ abule Idogbo wa lati ya aake ti nwọn yio fi ge igi ninu igbo ṣugbọn iya arugbo kan ti nwọn ri kọ lati ya wọn ni aake na.

Siwaju si i, irohin sọ pe lẹhin eyi ni arugbo na kọri si oko rẹ. Ṣugbọn bi o ti nlọ l'ọna oko na ni o ri awọn enia kan ti o nfẹ bo ohun kan ti o jọ posi oku mọlẹ.

Nihin ni arugbo na ti sare pada wa si abule ti o si sọ fun baale rẹ pe oun ri awọn enia kan ti o nsin oku enia, ki o ma jẹ pe nwọn yọ enia kan pa ni nwọn wa nbo oku rẹ mọlẹ nibẹ.

Irohin sọ pe nihin ni baale iya na ati gbogbo ọkunrin abule na ti dorikọ ọna igbo na, ọwọ wọn si tẹ ọkan ninu wọn, awọn yoku ti salọ

Nihin ni nwọn ti fi ọrọ na to awọn Ọlọpa leti.

Awọn Ọlọpa gbe seefu na wa silu Ibinni, nibi ti nwọn ti ṣi i ti nwọn si ri i pe gbogbo owo ti nwọn gbe na pe perepere sibẹ.

Bayi, awọn Ọlọpa ti tun ri awọn mẹrin mu bẹẹ ni Ọga Olọpa Ipinlẹ na si ti kan saara si awọn ara abule Idogbo fun iwa ifọwọsowọpọ wọn, o si ti fun wọn ni ẹbun ti o jọju l'ori ọrọ na.

# Sodeinde

(Lati Oju Ewe Keje) ba Ọgbẹni Ṣodẹnide kanlẹ. O ni eyi gan–an l'o jẹ ki o kowe ibalorukojẹ nipa ile iṣẹ ẹlẹjọ oun si Cooperative Bank.

Nitorina, Agbẹjoro na Ọgbẹni Afẹ Babalola, lẹhin ti o ti fi opolopo ẹsẹ ofin gbe oro rẹ lẹsẹ ro ile ẹjo giga na lati da Ọgbẹni Ṣodẹnide l'are l'ori ẹjo na.


OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE ERỌ ARAMỌNDA KAN DE.
ẸRỌ NA NI A NPE NI





**Solo Lawn Mower (N266.00)**

(EYI NI ẸRỌ TI A FI NGEKO)

Meji iru ẹrọ yi ko si rara
Ni ilẹ Naijiria.
Bi oko ti le wu
Ki o kun tabi pọ to
Ko jẹ nkankan l'oju ẹrọ na,
Ni kiakia ni yio pari rẹ.
Iwọ ti o ni ọgba l'ayika ile rẹ,
Ati ẹnyin alaṣẹ ile iwe,
Ẹrọ yi ni ki ẹ maa lo.
O dun i geko pupọ,
O si ni alopẹ.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
₦266.00 pere ni.
Tete wa ra tirẹ ni:

**Western Nigerian Technical Company Limited**

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

WENTEC 1955


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/4368 Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017.